Funded by
the European Union

INEC

# ÌTÓNI FÚN ENI TÍ Ó FẸ DÌBÒ FÚN ÌGBÀ ÀKỌ́KỌ́




Njẹ́ ìgbà àkọ́kọ́ rẹ nìyí láti dibó? Àsìkò lèyí fún ẹ láti kó ipa tiẹ nínú ètò ìdarí àti ìjọba àwarawa ilẹ̀ Nàìjíríà.

## 1. RÍ DÁJÚ PÉ O FI ORÚKỌ SÍLẸ̀

O gbọdọ̀ forúkọ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olùdìbò kí àǹfààní tó wà fún ẹ láti dìbò.

## 2. MỌ IBÙDÓ ÌDÌBÒ RẸ

Ó gbọ́dọ̀ mọ ibùdó tí wa ti dìbò kí ọjọ́ ìbò tó dé kí o sì mọ bí ó ṣe tètè dé ibùdó náà.

## 3. MÚ KÁÀDÌ ÌBÒ RẸ (PVC) LỌWỌ́:

O gbọ́dọ̀ mú káàdì ìbò rẹ dání torí ó ṣe pàtàkì láti lè ṣe àyẹ̀wò gẹ́gẹ́ bíi olùdìbò.

## 4. SE ÀYẸ̀WÒ ARA RẸ

Wọn yóò ṣe àyẹ̀wò rẹ gẹ́gẹ́ bíi ojúlówó olùdìbò kí o tó gba ìwé ìdìbò.

## 5. DI ÌBÒ RE

DÌBÒ fún ẹni tí ó bá wù ẹ lórí ìwé láìsí ìmọ̀sí ẹnikẹ́ni. Ra ìwé ìbò rẹ ki o sì fi si inú àpótí ìdìbò. Ìbò kan fún enikan péré ni.

## 6. TẸLẸ ÒFIN

O kò gbudọ ta ìbò rẹ, O kò gbudọ ṣe jàgídíjàgan, O kò gbudọ ṣe ìdúnkoko sí ẹnikẹ́ni, Ri dájú pé o tẹle gbogbo ìlànà tí ó wà nílẹ̀.

## 7. RÍRÍ DÁJÚ PÉ ÀLÀÁFÍÀ WÀ

Ìkópa nínú ètò ìdìbò kò sí fún wàhálà tàbí. Dìbò pẹ̀lú àlàáfíà kí ó sì bọ̀wọ̀ fún gbogbo ènìyàn.

## JẸ́ KÍ ÌBÒ RẸ DI KÍKÀ

Ìkópa gbogbo ènìyàn ní àsìkò ìbò ní o máa ń jẹ́ kí ètò ìjọba àwarawa dùn. Rìí dájú pé o kó ipa tìrẹ.

EU SDGN
European Union Support to Democratic Governance in Nigeria (EU-SDGN) Programme
www.eusdgn.org

IMPLEMENTING PARTNERS
DAI
PLAC
KUKAH CENTRE
IPC
CEMESO
ElectHER
TAF Africa
SOS CHILDREN'S VILLAGES

Funded by the European Union


# BÁWO NI O ṢE LÈ MỌ IBÙDÓ ÌDÌBÒ RẸ

Ìbò dídì bẹ̀rẹ̀ nípa mímọ ibi a ti fẹ́ dìbò.



## YẸ OJÚ ÒPÓ AYÉLUJÁRA ÀJỌ OLÙDÌBÒ WÒ

Lo àwọn ohun àyẹ̀wò rẹ lórí ayélujára àjọ olùdìbò láti mọ ibùdó tí wa ti dìbò.




## WO ORÍ KÁÀDÌ ÌDÌBÒ RẸ

Àlàyé nípa ibùdó ìdìbò rẹ, ríi dájú pé o mú dání ni ọjọ́ ìdìbò.



## LO ÀTẸJÍṢẸ TÀBÍ OJÚ ÒPÓ USSD

Ṣe àmúlò àtẹ̀jíṣẹ́ tàbí ojú òpó USSD láti mọ ibi tí wàá tí dìbò tí yóò sì yá kánmọ́kánmọ́.



## YỌJÚ SÌ IBÙDÓ ÀJỌ OLÙDÌBÒ AGBÈGBÈ RẸ

Lọ sí ibùdó àjọ olùdìbò tí ó súnmọ́ kí àwọn òṣìṣẹ́ àjọ náà le ràn ẹ lọ́wọ́ láti mọ ibùdó ìdìbò rẹ.



## WO PÁTÁKO ÌRÒYÌN

Wọn máa ń lẹ orúkọ àwọn ibùdó ìdìbò mọ́ ojú pátáko ìròyìn tí ó wà ní àyíká ìlú tàbí ní ibùdó ilé iṣẹ́ ìjọba ìbílẹ̀.

## OHUN TÍ A GBỌ́DỌ̀ MÁA RÁNTÍ LỌ́JỌ́ ÌBÒ

- Tètè dé ibùdó ìbò
- Mọ ibùdó ìbò rẹ
- Tẹ̀lé àwọn àlàkalẹ̀ ìlànà tí ó yẹ
- Dúró pẹ̀lú àlàáfíà

## GBÁRADÌ

- Mọ ibùdó ìbò rẹ
- Jẹ́ kí ìbò rẹ di kíkà


IMPLEMENTING PARTNERS

European Union Support to Democratic Governance in Nigeria (EU-SDGN) Programme
www.eusdgn.org

Funded by
the European Union

# BÍ A ṢE Ń DÌBÒ

Ìlànà tí a yóò Tẹ̀lé láti
ríi dájú pé ìbò wa di kíkà






## 1. DÉ LÁSÌKÒ

Ríi dájú pé o dé ibùdó ìbò lójú ọjọ́, èyí yóò sì jẹ́ kí o tètè dìbò.




## 2. ṢE ÀFIHÀN KÁÀDÌ ÌDÌBÒ RE:

Rii dájú pé o ṣe àfihàn káàdì ìbò rẹ fún àwọn òṣìṣẹ́ àjọ olùdìbò gẹ́gẹ́ bíi ojúlówó olùdìbò.



## 3. SE ÀYẸ̀WÒ RẸ

Wọn yóò ṣe àyẹ̀wò rẹ fínnífínní, kí ó sì wà ní ifarabalẹ̀.




## 4. GBA ÌWÉ ÌDÌBÒ RẸ :

Gba iwe ìbò rẹ lọ́wọ́ òṣìṣẹ́ àjọ olùdìbò, má tíì ohunkóhun si.





## 5. DI ÌBÒ:

Wọ inú kulu ìbò kí o sì di ìbò rẹ dáadáa yàgò fún àṣìṣe.




## 6. FI ÌWÉ ÌBÒ RẸ SÍLẸ̀

Ká ìwé ìbò rẹ ki o sì fi sí inú àpótí ìbò dáadáa.



## 7. FI Ọ̀DÀ KUN ÌKA RẸ

Wọn yóò fi ọ̀dà ṣe àmì sí ìka rẹ láti fi hàn pé ó ti dìbò kí olùdìbò sì má dìbò kọjá èèkàn.

## ẸTỌ́ RẸ NI KÍ O DÌBÒ

DÌBÒ PẸ̀LÚ ÀLÀÁFÍÀ
DÌBÒ BÍ ỌMỌLÚWÀBÍ

EU SDGN
European Union Support to Democratic Governance in Nigeria (EU-SDGN) Programme
www.eusdgn.org

IMPLEMENTING PARTNERS
DAI
PLAC
KUKAH CENTRE
IPC
CEMESO
TRUST FUND
ElectHER
TAF Africa
SOS CHILDREN'S VILLAGES

Funded by
the European Union

# ÌRÒYÌN KÒTỌ́ LÈ ṢE ÀKÓBÁ FÚN ÈTÒ ÌJỌBA ÀWARAWA

Mọ òtítọ́ kí ó sì dáàbò bo ìbò rẹ.

## Kini ìròyìn kòtọ́?

Irọ́ tàbí ìròyìn asinilọ́nà láti si àwọn olùdìbò lọ́nà, yálà èyí tí a mọ̀ọ́mọ̀ gbé síta tàbí èyí tí a kò mọ̀.

## Báwo ni a ṣe lè dá ìròyìn kòtọ́ mọ̀

Ẹ ṣe ìwádìí orísun ìròyìn náà

Ẹ ṣe ìwádìí pẹ̀lú àwọn ojúlówó ilé iṣẹ́

Ẹ ṣọ́ra fun àwọn àkòrí asinilọ́nà

Ẹ sora fun àwọn àwòrán asinilọ́nà

## Oríṣi ìròyìn kòtọ́

Ayédèrú ìròyìn orí ìtàkùn ìdọ́rẹ́pọ̀

Ọ̀rọ̀ òkèèrè tí kò fidí múlẹ̀

Àwòrán, fọ́nrán tàbí ayédèrú ìwé tí wọn tí dá ọgbọ́n sí.

## Kíni ó yẹ kí ẹ ṣe

Ẹ ṣe ìwádìí òdodo kí ẹ tó gbé ìròyìn náà síta

Bí kò bá dá yín lójú ẹ má gbé síta

Ẹ ṣe ìfisùn àwọn ohun tí ẹ fura sí pé kòtọ́

## Kini ìdí rẹ̀?

Ó máa ń si olùdìbò lọ́nà

Ó máa ń dá àríyànjiyàn sílè tí sì le fa wàhálà

Kii jẹ ki awon ènìyàn ní ìgbàgbọ́ nínú ìlànà ètò ìdìbò.

## Ojúṣe gbogbo wa

Àwọn oníròyìn gbọ́dọ̀ ṣe iṣẹ́ wọn bí ó ti yẹ

Àwọn ará ìlú gbọ́dọ̀ bèèrè fún òdodo àti àkóyawọ́

## ORÍ ÒDODO NI ÈTÒ ÌJỌBA ÀWARAWA TI LÈ ṢE DÁADÁA

Yàgò Fún Ìròyìn Kòtọ́

Ṣe Àgbéga Ìròyìn Tí Ó Jẹ́ Ojúlówó

European Union Support to Democratic Governance in Nigeria (EU-SDGN) Programme
www.eusdgn.org

IMPLEMENTING PARTNERS